**OWE**

A NJUWỌN ko se wi tejo ija llara ko tan boro

Agbalagba ti yio tẹ ile tutu yio da omi siwaju. Igba ki i to lọ bi orere aiye ki i to lọ bi opa ibon.

# Irohin Yoruba

No. 762 JANUARY 13 — JANUARY 19, 1960 Kobo Meji (2D.)

**LAKAYE ỌRỌ**

OJU Oluwa mbe lara awọn olododo, eti Rẹ si si si igbe won. Oju Oluwa kan si awọn ti nse buburu lati ke iranti won kuro lori ile. Awọn olododo nke, Oluwa si gbọ, o si yọ won jade kuro ninu ise won gbogbo.

# ALAKOSO IGBIMỌ IJỌBA GẸẸSI DE

EKO.

NI irolẹ ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi ni Ọgbẹni Harold Macmillan, Alakoso Igbimọ Ijọba Gẹẹsi ati iyawo rẹ Ọlọla Iyaafin Dorothy Macmillan ba Ọkọ-ofurufu gunlẹ si Eko fun ibẹwo ọjọ mejọ ti nwọn fẹ ṣe ni Naijiria. Ki nwọn to gunlẹ ni Ọlọla James Robertson, Gomina-Agba Apapọ Ijọba Naijiria ati aya rẹ pẹlu Ọlọla Alhadji Abubakar Tawafa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria pẹlu awọn Iriju Apapọ Ijọba Naijiria ti duro de e lati gba a lalejo ni Ebute Ọkọ-ofurufu Ikẹja.

Gbara ti o ti gunlẹ ti Gomina-Agba ati aya rẹ ti ki i ku-abọ ni o ti lo yẹ awọn Ẹgbẹ Ologun ti nwọn wa ṣe eye fun un wo, lẹhinna ni Alhadji Tafawa Balewa fi awọn Iriju Ijọba ti o wa pade Ọlọla na han an, o si ki gbogbo wọn lọkọọkan pẹlu awọn enia pataki pataki ti nwọn wa pade re. Lẹhinna ni on pẹlu iyawo rẹ ba wọ moto Gomina-Agba wa si Afin Gomina-Agba na l'Ẹhingbẹti l'Eko, gbogbo awọn enia ti o to si oju ona ti moto Ọlọla na gba kọja ni nwọn bẹrẹsi juwọ si i ki i kuabọ, on na si nda wọn lohun ifipa jijuwọ si wọn lọtun-losi.

Ọrọ-ikini-kuabọ ti Ọlọla Alhadji Tafawa Balewa Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria fi ki Ọlọla na kuabọ ni pe:—"Awa ara Naijiria dupẹ lọwọ rẹ fun itara ti o ni si idagbasoke ilu wa" Ogbẹni Macmillan si fesi si ọrọ Ọlọla Abubakar pe, on ati iyawo on ni inu didun pupọ lati ṣe ibẹwo Naijiria ti awọn ti ngbọ okiki rẹ lati ọjọ pipẹ

## Ẹniti o yinbọn ṣereṣere lu enia fi ogun pọnun tanran

IBADAN.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ (Grade "B" Customary Court) Ibadan kan ṣe idajọ pe ki ọkunrin ọdaran kan, Arasi Adebisi, Idikan Ibadan fi ogun pọnun (£20) tanran si Kotu tabi kio lọ si ẹwọn oṣu meji nitori ti o jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun pe, o yin ibọn ṣereṣere rẹ lu ẹnikan ti o njẹ Yesufu Adeniyi, o si dogbẹ si i lara ni alẹ aisun odun Keresimesi ti o kọja yi.



Ọlọla Macmillan, Alakoso Igbimọ Ijọba Gẹẹsi njuwọ si gbogbo awọn enia ti nki !

**Awolọwọ njuwọ si awọn ti o nyombo rẹ**



# ỌJỌ NLA NI ỌJỌ NA L'EKO

NI arọ ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi ... agogo mọkanla ni awọn aṣoju Igbimọ Aṣofin A... Ijọba Naijiria bẹrẹ ipade ati Ajọ Igbimọ Giga Titun (Assembly of Senators). Awọn mẹrinlelogoji ni awọn igbimọ ti o wa ninu Ile Igbimọ Giga Titun yi, Dọkita Nnamdi Azikiwe ni awọn Igbimọ Giga na yan ni Alaga, nwọn si yan Ọba Adele Keji ni Obakeji rẹ.

Ni kutukutu arọ ọjọ na nṣe ni gbogbo awọn ara Eko bẹrẹsi ro kuku-kẹkẹ lati lọ pade aṣiwaju ẹgbẹ oṣelu wọn. Awọn obirin ọlọja Eko kọ patẹ ti gbogbo wọn wọ aṣọ ẹgbẹ-jọda pẹlu oriṣiriṣi ilu ti nwọn si njo mukẹ-mukẹ bi ẹni ajọyọ Ọdun Keresimesi tabi Ileya. Ẹgan ni hẹ! O ye Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ni ọjọ na: nitori titi o fi de Ile Igbimọ na ni ariwo nta lọtun- losi ti nwọn pe Awo! Awo!!

Gbogbo awọn Aṣoju Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria na ti o wa kakiri lati awọn ilu Naijiria ni o ṣe pabambari ẹṣọ, nitoripe bi nwọn ti mbọ silẹ ninu moto ni gbogbo awọn enia nyombo wọn. Awọn miran wọ agbada ẹtu, awọn miran wọ agbada sanyan awọn miran wọ agbada lesi, awọn miran lọṣọ mo idi bẹni awọn miran si wọ aṣọ Oyinbo ti o gbamuṣe bakanna.

# Ijębu-Ode yan Awujalę



Awọn Ijębu-Ode yan Ọmọ-Ọba Sikiru Layọde Adetọna ni Awujalę Ijębu-Ode

## Ọkunrin kan di ewele sinu igbo

KABBA.

LAIPE yi ni gbogbo awọn ara Abule Agirigbọn-Oke sa kuro ni abule na tọmọ tọmọ nigbati nwọn ri ara abule wọn kan Paul Afonka, ẹniti nwọn sọ wipe o junu sinu igbo ti nwọn si ti nwa kiri fun odidi ọjọ mẹta ṣugbọn nigbati nwọn fi oju kan an o ti di abami-enia

Ori rẹ ti sunki, o si ri tombolo, o ni ọmu nla kan bi ti obirin, ẹsẹ rẹ tobi, apa osi rẹ si tinrin. Fun wakati mejidilogun ni awọn adhunṣe ti awọn ẹbi rẹ pe fi sa agbara wipe ki o le lanu rẹ sọrọ ṣugbọn ko le sọrọ. Awọn ẹbi rẹ si ti mu u kuro ni abule na lọ si ibi ipamọ.



Atabuređi yi fi owo rẹ pamọ si

BARCLAYS BANK D.C.O.

Iwọ paapa le bẹrẹ si fi owo rẹ pamọ sibẹ lati oni lọ.

## *Adajọ sọ ẹniti o ji şile meji sẹwọn oşu mẹsan*

ỌWỌ.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oşu ti o kọja yi ni Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ (Grade "B" Customary Court) sọ Nwangbu Okigwe, ẹni ọdun mẹrindinlogoji ti awọn ọlọpa pe ni "apẹlẹwọn" sẹwọn oşu mẹsan nitoriti o jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba a şe.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa na ro nipe ọdaran na lọ si Ibudo moto akero ni ọjọ Aiku ti işe ọjọ kọkandinlogbọn oşu kọkanla ọdun ti o kọja o si ji ọkunrin kan ni apo-owo pẹlu şile meji. Nigbati o fẹ fi owo ti o ji ra onjẹ ni Ijębu-Ọwọ ni awọn ọlọpa ba mu u.

## Ẹniti o ba iyawo oni-iyawo tage fi £25 tanran

IBADAN.

LAIPẸ yi ni Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ (Oke-Arẹ Customary Court) sọ ọdaran kan, Saliu Akanbi, ẹni ọdun mẹtadilogun si ẹwọn oşu mẹta nitoripe o ji agbebọ adiẹ ati akukọ kan gbe. Ẹjọ ti ọdaran na ro ni pe on fẹ fi awọn adiẹ mejeji yi şe iranti oku baba on, ki on le jẹ ẹni-iyi loju awọn ọmọlẹbi on.

## Adajọ sọ ẹniti o ji adiẹ gbe sẹwọu

IBADAN.

LAIPẸ yi ni Adajọ Kotu Ibilẹ (Oke-Arẹ Customary Court) Ibadn şe idajọ pe ki ọdaran kan, Ayọola Ajagbe, ẹni ọgbọn ọdun lọ san ponun mẹdọgbọn si apo Ijọba tabi ki o lọ s'ẹwọn oşu meji nitoripe o ba iyawo oni-iyawo tage pẹlu agbara ti o si fi di ija.

# Ewele ẹlẹsẹ-mẹfa wọ ọja

IJẸBU-ỌDE.

NI deede agogo mẹsan owuro ọjọ Ẹti ti işe ọjọ kini oşu kini ọdun yi ni Ewele ẹlẹsẹ-mẹfa kan w'ọja Irete, Ijębu-Ode, lẹsẹkẹsẹ ni ọja na tuka pẹe ti gbogbo awọn ero ọja nsare asa-şubu-lebu. Nigbati awọn Ijọ ti o wa josin ọdun titun ninu Şọọşi "Anglican", Irete gbọ irohin yi, ere ọlomọ-gbomọpọn, onigun-kagun-ko ni awọn abiyamọ ti o le ni ọgọrun enia nsa fi wa awọn ọmọ wọn kakiri, bi Şọọşi na ti kun to, lẹsẹkẹsẹ ni o tu yanga.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn ọdẹ-onibọn ilu na ti o le ni ogun enia ti gbarajo ti nwọn si bẹrẹsi yinbọn lu Ewele-ẹlẹsẹ-mẹfa yi, şugbọn ọta-ibọn wọn ko turun lara rẹ, nşe ni o duro ko-ngbari ti o nwo wọn koran, ti o si fi ara ti opo kan ni ọja na o to agogo mọkanla abọ ni ida-san ki o to wọ igbo lọ.

Awọn agbaagba abule na sọ lẹhin ti Ewele na ti lọ tan pe, ki işe alejo si awọn, ewele na ti nwa si ilu na ti pẹ, nwọn tun sọ pe, ọdọ-ọdun ni ewele na ma a nwa pa ọmọde kọọkan jẹ. Ọkan ninu awọn ọdẹ sọ wipe, ni-gbati awọn dẹ takute fun un ni oşu kẹta ọdun ti o kọja yi, ewurẹ ni takute na mu.

# AKIYESI

**Ẹnikẹni ti o ba mọ itan awọn Ọba ile Yoruba, iba şe eyiti o ti ku ni tabi eyiti o wa laaye, ki o kọ ọ sọwọ, tabi bi nwọn ti şe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu itan işẹdalẹ Yoruba. A o si tẹẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ ku işẹ o.**

**OLOTU**

MULTIVITE

*KORO EGBOGI IMARALE . .*



fun awọn aboyun ati abiyamọ . .

Awọn aboyun ati awọn abiyamọ ni lati mu Koro egbogi Multivite meji lojojumọ: nitoripe Multivite ni egbogi imarale "D" ninu, eyiti o nşe iranlọwọ lati jẹki ẹsẹ awọn ọmọ-tuntun to si okankan ki o si lagbara.

Koro egbogi MULTIVITE tun ni: Egbogi Imarale "A": ti o nran enia lọwọ lati le fi ara da awọn aisan bi otutu-iba ati ayọkẹlẹ. Egbogi Imarale "B" eyiti o nşe iranlọwọ lati şegun aarẹ ọpọlọ-ori.
Egbogi Imarale "C" ti o nran awọ-ara lọwọ lati mọ gaara ki o si jolọ, o si njẹki ehin fidi-mulẹ ki o si lagbara.




BDH THE BRITISH DRUG HOUSES LTD. LONDON

Distributed by branches of THE UNITED AFRICA CO. OF NIGERIA LTD.

## Adejọnwo sinku iya rẹ

**Ọtẹrẹ l'ẹba Abẹokuta.**

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kokandinlogun oṣu kejila odun ti o koja yi ni Estehr Adejonwo ṣe isinku iya rẹ ti o jalaisi laipe yi. Nwọn ṣe akanṣe isin-iranti ologbe iya rẹ na ni Ṣọọsi "All Saints Anglican Ọtẹrẹ.

Lẹhin isin ọpọlọpọ enia ti o wa si ibi aṣeye na tẹle ọmọloku lọ si ile nibiti o gbe fi jijẹ ati mimu tẹ wọn lọrun. Inawo ọjọ na pọ pupọ.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ ni awọn Ọgbẹni A. A. Oyedele, J. A. Ọdẹdina, Liadi Shokẹyẹ, T. Ogundimu, B.Olumuyiwa, R. Awoyẹmi, J. O. Oyenẹyẹ, Ben Olowoyo, J. O. Bankole ati E. O. Ijaduọla.

# Aboyun kan ni Iyan ni o wu on ninu

ILESHO.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni obirin aboyun kan ọmọdunbi Ogundare ti o fẹ kọ oko re Folorunshọ Akẹju ti o nṣiṣẹ ni Wesley Guild Hospital" ile sọ fun Adajọ Kotu Ibilẹ pe, on ko mo pe oyun ni o wa ninu on, o sebi iyan ti on je ni o wu on ni'nu, ni gbogbo ero Kotu ba kunlẹ si erin arintakiti. Ogbeni Ọlatunji Ogunbiyi ni agbẹjọro obirin na ti nto o sọna.

O si tun se alaye fun adajo na pẹ idi ti on fi fẹ ko ọko on na silẹ ni pe, o ya ọlẹ, ko fẹ se Iṣẹ agbara, nitoripe baba on n' o nfun on pelu rẹ ni onjẹ jẹ ati ọmọ odun mẹfa ti on bi fun un. O ni on tun lọ gba awin egberun (1,000) ebuiṣu ati ada kan fun un lati fi da oko, o lọ se gbogbo ebu-iṣu na jẹ tan, ti o si da gbese si on lọrun, nwọn kunlẹ serin ni kotu.

Nigbati o ro ejọ tan ti Adajọ na si ri i pe ọkọ rẹ na koja a niyan, ni o ba fun un lase pe ki o kọ ọkọ na silẹ, ki o si san ponun mẹdogun (£15) owo idanọ ọko na fun un pada.











# Oti Guinness
*Nfun ni*
# LAGBARA




**ohun ti o dara julọ**
**l'a fi ṣe ọti Guinness—**
**eyiti o daraju na**
**l'o ye ọ!**

**Didara ọti Guinness**
*to iye owo ti o san!*

**ni Gbigbona**
**tabi ni tutu gẹgẹbi**
**o ba ti fẹ**

---




# THAMES TRADER*
## yio ṣe iṣẹ rẹ .. DARAJU!

## 50 ati 70

Iṣẹ-kiṣẹ ti o wu ki o jẹ, fagadaga ni THAMES TRADER ti o gunlẹ dada yio ko awọn ẹru na. Ile moto na ṣe e yipada kiakia ni Wangonu-ẹru-Nla tabi ni eyiti o ntakiti ẹru lọna mẹta . . . Ile mọto ti o le yipada dada yi ni ohun ti o nfẹ, lati ma a ti ko awọn inkan-ọsin. O rọrun lati tunṣe dada. TRADER 50 ati 70 yara lati ṣiṣẹ kiakia laisi inawo pupọ . . . O yara pupọ lati ma a lọ-alọbọ . . . O si yara pupọ lati sun ẹrẹ wa ile.



Obadun agbara inilẹ ... ... mẹta ni. Oni-70 le ko ẹru de iwọn 6,650 ...



* Awọn Mọto FORD miran

**J. ALLEN & CO. LTD** LAGOS, ABA, BENIN, ENUGU, IBADAN, JOS, KANO, KADUNA, PORT HARCOURT, ZARIA



ᴍworan yi nı ti Oıoye ◌bafẹmi Awoıọwọ, Oıorı ◌gbẹ Afẹnifẹre ati ti Aya rẹ, Oloye H.J.D. Awolọwọ ti nwọn ya ni Ikẹja pẹlu ọmọbirin wọn, Ọmọtayọ nigbatı o nlọ si ilu Oyinbo fun ẹkọ. Alufa Solarin ni o wa ni ọwọ ọtun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

# Ọdẹ kan yinbọn pa obirin, o ṣebi kẹtẹkẹtẹ ni

ILORIN.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni moto gbokugboku ọlọpa Ijọba Ibile Ilọrin gbe oku iya arugbo kan, Ayisatu Amokẹ wa si Ilọrin ati abule Ẹkundayọ ni Oke-Ọdẹ. Awọn ọlọpa sọ wipe, nigbati iya arugbo na lọ ṣa ira-ekurọ ninu igbo kan Abule Ẹkundayọ, ni ọdẹ kan ti o njẹ Suberu Alabi ba yin in ibọn nigbati nwọn fi nṣe ọdẹ kakiri inu igbo na ni ọjọ kini oṣu kini ọdun yi.

Ejọ ti ọkunrin ọdẹ na, Suberu Alabi ro fun awọn ọlọpa ni pe nigbati on ri iya arugbo na nibiti awọn gbe ti nṣe ọdẹ lọ, o dabi kẹtẹkẹtẹ loju on, ni on na fi yinbọn fun un, ṣugbọn nigbati on gbọ igbe enia kan ti o sọ wipe, "Iwọ ti o yinbọn lu mi, ma a bọ wa nihin o" ni on fi mọ wipe ibọn on pa eeṣi ni. Awọn ọlọpa si gbe e timọle nigbati o rojọ tan.

## Ole ji kẹkẹ-Rali pelu ọgọta pọnun lọ

ILESHA.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni ole kan ji Kẹkẹ-Rali (Raleigh Bicycle) kan ati pọnun mọkanlelọgọta (£61) owo ti o wa ninu apo ti nwọn gbe kọ ara kẹkẹ na lọ mọ ọga onimọto kan lọwọ ni Posu Ọfisi Ilesha nitoripe ko ni ifura tẹlẹ pe awọn ole na nṣọ on kakiri.

Nigbati Ọga onimọto na jade lati Posu Ọfisi ti o ti lọ ra ọja ni o ba fẹ kẹkẹ rẹ ku pẹlu apo owo o kigbe fo o, o si bẹrẹsi lu ara rẹ ni ilukulu, ṣugbọn "ẹpa ko boro mọ", ole ti gbe kẹkẹ rẹ lọ towo-towo. Ki Oluwa rere gba wa lọwọ ẹniti o nṣọ wa lati ṣe ijamba fun wa ti a ko mọ.

**Ẹ ma a ka Iwe IROHIN YORUBA niqbagbogbo fun irohin aladun**








Awọn obirin ọlọja ti nwọn njo ti nwọn nyọ wa pade Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ pẹlu aṣọ ẹgbẹjọda wọn



Awolọwọ nki gbogbo awọn enia nigbati o fẹ wọ Gbọ'ngan Apejọ Ipade Igbimọ na

## Igbimọ Ibilẹ gb'ogun ti awọn ti ko san owo-ori

IBADAN,

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ karun oṣu kini ọdun yi ni deede agogo mẹfa owurọ ni awọn ọlọpa Igbimọ Ibilẹ Ibadan dide ti nwọn pin ara wọn si gbogbo adugbo pataki pataki lati ma a mu awọn ti ko ti san owo-ori wọn ti odun ti o kọja yi, ogunlogọ enia ni nwọn si ti ri mu ti nwọn fi moto ko won lọ si ile iṣẹ awọn ọlọpa ni Oke Mapo.

Ọkan 'nu awọn oṣiṣẹ Igbimọ Ijoba Ibilẹ sọ fun awọn oniwe irohin wa pe lati nkan bi ijẹwa ti iṣe ọjọ Aje ti ọsẹ ti o kọja ni awọn ti nri ogunlogọ awọn enia ti nwọn wa nsan owo-ori wọn ti nwọn ko ti fẹ san ri. Awọn Igbimọ Ibilẹ na paapa ṣe ikede pe ninu £532, 360 ti awọn ni lati na ninu ọdun ti a bọ si yi, idaji o le diẹ ni awọn ṣẹṣẹ ri gba.


ONISOWO IWE

ANI AWỌN ORIṢIRIṢI

ẸGBẸGBẸRUN IWE

FUN AWỌN OLUTAWE

NI ẸDIN WO

ESA (NIGERIA) LTD

P. O. BOX 253 YABA LAGOS

PRINCES HOUSE TINUBU SQUARE LAGOS





Ọmọde yi koro, ko ni imi ninu, agbara kinun ni o si ni nitoripe ẹba pẹlu ẹkọ nikan ni nwọn fi mbọ ọ





AMAMA ni nwọn fi nkun onjẹ ọmọ yi o si ni alafia ati ilera ni igba gbogbo



AMAMA nfun ni ni agbara



fi AMAMA kun onjẹ nigba gbogbo

Manufactured by Glaxo Laboratories (Nigeria) Ltd., Apapa, Lagos.

Trade enquiries: R. H. Harding & Co. Ltd., Lagos, Aba and Kano.
Sub-distributors in Ibadan: Standard City Chemists.


Printed and published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd. 5/7. Apongbon Street, Lagos (Editorial and Advertisement Office) Telphone 23675/23676. Fun owo "Irohin Yoruba" odun kan. Eko sile mejo ati kobo mejo (8/8d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile metala (13s.) Olotu S. M. ADEMUYIWA 2 Idumagbo Street Idi-Oro